# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 883 LAGOS SATURDAY AUGUST 24 - AUGUST 30 KỌBỌ MEJI (2D) 1963


### Omo Egbe Npase, Baba Egbe Nworan :

# Rogbodiyan Awon Egbe NCNC Di Awo-rerin Awon Ara Ilu

IBADAN—Kosi ẹniti o le sọ asọtẹlẹ ibiti rogbodiyan ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Alakukọ Ipinlẹ Iwọ Orun yio yọri si ṣugbọn a gbọ wipe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti o wa ni ile igbimọ awọn aṣofin Ipinlẹ Iwọ Ọrun ti pinṣi meji, awọn kan wa fun Ọgbẹni Fani-Kayọde, awọn apa keji ni Ọgbẹni Olu. Akinfosilẹ ni awọn a ba lọ. Awọn enia kan ni ọrọ ẹgbẹ YORUBA PARAPỌ ti nwọn ngbero lati da silẹ gẹgẹbi ẹgbẹ oṣelu ni o fa rogbodiyan na ṣugbọn agbalagba ti o mọ idi rẹ ni eyi nikan kọ.

Awọn agbalagba ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti dide lati pari ọrọ na; a gbọ wipe nwọn ba Fani-Kayọde wi nipa lilọ ti o sare lọ si Ẹnugu lati sọrọ rogbodiyan na fun baba ẹgbẹ wọn Dokita Okpara. Nwọn ni kọ ju okan ti a le pari ni Ibadan lọ, A tilẹ gbọ wipe Dokita Okpara paapa ni on ti gbe gbogbo ọrọ ẹgbẹ ti ẹka Ipinlẹ Iwọ Orun le Ọgbẹni Benson lọwọ wipe on ni ki nwọn ma ba sọ ọ.

---

Ologbe Oyinbo na jẹ ẹniti o lawọ pupọ, Ọpọlọpọ aimọye owo ni o ti na fun awọn akẹkọ kakiri ilu Oyinbo ati ilẹ enia dudu wipe ki nwọn ma lo fun la t i wa ẹgbogi fun anfani ara aiye.

Owo ti Ologbe na ni kuro ni kika o si jẹ ọkan ninu awọn ti o ni owo julọ laiye ti nwọn npe orukọ wọn ni Milọnia (Millionaire) Orun re.

## Ikan Ninu Awon Qlowo Aiye Ku

LONDON-Ikoko nla kan fọ ni ilu Oyinbo ni owurọ ana, ọkan ninu awọn olowo aiye t nwọn npe orukọ oye rẹ ni LORD NUFFIELD jalaisi ninu ile rẹ. Ẹni ọdun marundelọgọrin ni Oloye Ọlọla Nuffield na, nwọn bi ni October 10 ni ọdun 1877.

William Morris ni ọlọla Nuffield yi njẹ ki nwọn to ti oye nla yi daa lọla. Nigbati o jade iiewe iṣẹ a ntun kẹkẹ basikulu ṣe (cycle repairer) ni o nṣe titi ti o fi di ẹniti o nṣe mọto-ayọkẹlẹ ti a npe ni MORRIS ni aiye atijọ. awọn mọto ti nwọn nṣe ninu ile iṣẹ Nuffield na ... ni nwọn npe ni CONSUL.

## Oloye Adelagun Goke Agba

EKO— Oloye Ajadi Adelagun, Ọtun Arẹ ilu Eko ti tun gun oke agba, irohin kan ti a tun gbọ nipa oloye ọtun Arẹ na ni ti Agba Oye AJIRỌBA ilu Eko ti Ọba Adele Keji ṣẹṣẹ fi jẹ ninu ọsẹ ti o kọja yi.

Oye Ajirọba kiṣe oye kekere ni ilu Eko, Ologbe Karimu Kọtun ni o kọ jẹ Oye na l'Eko iṣẹhin iku rẹ nwọn gbe e fun Alhaji Sadiku Sarumi.

Ọmọ Oye ni Oloye Ajadi Adelagun paapa ni ilu Eko nitoripe baba iya rẹ Ajasi Thompson ni o kọ jẹ Balogun ni ilu Eko ni ọjọ ti o ti pẹ.

Awa onirohin Ele i-Ọfẹ ki oloye ... o... ni ... ... ... oye na a ... ... .

---

KILOṢE TI AWỌN ṢỌJA WA KO LE KỌ AFARA?

## Dokita Obinrin Kan Ni On Fe Mo Idi Eyi

IBADAN— Dokita obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Irene Ighodaro ti o nṣe iṣẹ iwosan ni Ibadan ni o yẹ ... oju ma ti awọn ṣọja jagunjagun wa ti a na owo gọbọyi le lori lati ti wipe nwọn ko le kọ afara pajawiri si ọna Aiyetoro leti ilu Abẹokuta ti nwọn sọ wipe eyi ti awọn ara ilu na kọ lẹ wo nigbati awọn mọto kabiti ... ngun ori rẹ.

Dokita obinrin yi ni lati bi ọsẹ meji wa ni ikun omi ti sọ oju ọna meji ti o gba Abẹokuta de Eko ati Eko de Ikorodu di agbeti silẹ. O ni gbogbo awọn ara agbaiye ni nwọn nwo wa lati wo bi a ti nia gbara ... .

( Wo yoku loju ewe kejọ )

## Gbanjo! Okunrin Kan Lu Gbanjo Ara Re

SIDNEY—Nkan okan ninu aiye ti a wa yi, ọkunrin kan ni ilu Oyinbo ẹni ọdun mẹtadinlogoji polowo ara rẹ sinu iwe irohin kan ti o njade lojojumọ ti nwọn npe ni "SUN" wipe on wa obinrin kobinrin ti o ba lowo ọwọ ti yio ra on titetite ni ojidinlẹgọẹrun pọnun (£960) pere.

Ọkunrin na ti 'o ni ki nwọn fi orukọ bo on ni aṣiri ni on ti fi igba kan ri iyawo sile, o si ni ọmọ mẹrin fun on, ọkunrin meji obinrin meji.

(Wo yoku loju ewe kejọ)


## LAGOS RACE CLUB

The THIRD DAY August Race Meeting will take place on Saturday 24th August, 1963. First Race at 3. 30 p. m.

Sweepstake will be drawn on the numbers of Admission Tickets. 1st will be paid £2. 10/- 2nd £1 10/- and 3rd 10/-.

Also two Silver Cups will be presented to the best dressed Ladies in national Costume and Western dress on the last day of this meeting.

COME ONE COME ALL

Hon. SECRETARY
LAGOS RACE CLUB

# Ijọba Fe Ko Ogba Were Miran Si Yaba

EKO — Ijọba Apapọse ilẹ̀ Nigeria ngbero lati kọ ile iwosan tuntun miran fun awọn were, awọn enia ti uwọn ba nṣe gan-gan gan. Nwọn ni ile awọn were na yio gba to ojidinrinwo (360) ibusun. Minisita alamojuto eto ilera, Dokita M A Majẹkodunmi ni o sọrọ yi nigbati o nṣi ile iwosan tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ kọ ni Eky.

Dokita Majẹkodunm ni Ijọba tun ngbero lati kọ ile iwosan kan onigba ibusun (200) fun awọn itoju awọn ọmọde laipẹ yi. Dokita yi ni ile iwosan tuntun ti awọn wa si loni yi jẹ ti awọn ti yio ma tile wọn wa gba egbogi. ọkẹ marundinlogun poun (£300,000) ni awọn fi kọ ọ.

Ile iwosan na gba ẹgbẹrun awọn alaisan ni ijoko wọn, iyara mẹrinla ti enia le ri dokita werewere ni o wa nibẹ. Eleyi yatọ si apeti pako ti nwọn ti nfi joko r.

# Mosalasi Wo Pa Awon Imale Ni India

INDIA — Ọrun ya ni owurọ ijẹta ni ilu kan ni India nigbati Mosalasi kan ti awọn Imale nkirun ninu rẹ ya, ti o wo lu gbogbo awọn baba alasalatu ti o nkirun ninu rẹ ti o si pa ọpọlọpọ enia.

A gbọ wipe o to ọdunrun awọn enia ti nwọn pejọ sinu Mọsalasi na ti wọn nṣe asalatu lọwọ, awọn miran ngbadura, awọn mirun nkirun, ni ojiji ni ogiri Mọsalasi na ya, ti o si wolu wọn mọlẹ siba.

Ọgọrun enia ni nwọn gbe jade ninu alapa Mọsalasi na loku, ọpọlọpọ ni awọn ti o farapa ti nwọn ru lọ si ile iwosan ṣugbọn ki nwọn to de ile iwosan na ni ọpọlọpọ ti tun ku lọna ninu wọn. Nwọn ni o to ọkbọn ọdun ti nwọn kọ Mọsalasi na.

Olodumare ma jẹki a rin lọjọ ti ebi npa ọna.



# Awon Janduku Kan Sunle Orisha Ilu Ibo

ONITSHA — Awọn agba oloye ilu Onitsha ti lọ ba oga awon ọlọpa ilu Onitsha lati fi ẹjọ awọn janduku kan sun wipe nwọn nti awọn loju mọlẹ ntoripe gbogbo ile orisha awọn ni awọn janduku na ti fọ tan ti nwọn tun fi gbogbo nkan abalaiye ti awọn ko sibẹ jona patapata.

Awọn oloye ilu kan ti npe ni Ogbunike lẹba Onitsha ni nwọn kọ ni iru ẹsin bayi wa si iwaju ọga ọlọpa na. Nwọn ni ni oru ọganjọ ni awọn janduku na wa fi ina si ile orisha awọn, nwọn ni gbogbo ere abalaiye ti awọn mbọ ni nwọn ji ko, ti nwọn lọ ko da siru odo.

Ọga ọlọpa na ni nkan na ṣe on ni kayefi, o ni gbogbo rẹ ni on yio ṣe iwadi rẹ patapata. Bi o ti nsọ eyi lọwọ ni awọn ara Abatete tun ko ọrọ ile orisha ti nwọn sọ wipe awọn kan dana sun de.

Babalorisha ilu wọn ni gbogbo nkan ti awọn fi mbọ orisha OMALIKO ni nwọn ti kan ina si patapata. Nwọn ni iru nkan bayi ko ṣẹ̀ẹ̀ nilu awọn ri. Boya nwọn si fẹ ki orisha na ba wọn ja ni.

# Akiyesi

**E ma ka Iwe Irohin ELETI-OFE Losose. O kun fun Irohin Aladun;**

# Iyara Ilewe Omoba Oyinbo

**Omo Oba ilu Oyinbo obinrin ti nwon npe ni Anne di omo odun metala ninu osu yi, o si ni lati beresi lo si ile eko, ti nwon npe oruko re ni Benenden School ni ilu Kent. Iyara ti omo oba na pelu awon akeko egbe re yio ma sun si ni e nwo aworan re ninu iwe irohin yi.**

# Alaye Eto Ilera Ti Ijoba Fe Gbe Jade Fara Eko (5)

Gẹgẹbi ilera ti a ṣe fun ẹyin ọkawe wa wipe gbogbo iwe alaye ijọba te sode lori eto ilera tuntun ti minisita alamojuto eto ilera fẹ gbe jade ti awọn enia kan tako ni ao tẹ jade fun yin. Eleyi ni a o fi ṣe ipari iwe alaye na

## Anfani Nla

Lati bi ọsẹ marun ti a bẹrẹsi tẹ iwe alaye na jade, a ti fi han yin wipe anfani nlanla ni o mbẹ ninu eto ilera na.

Nwọn ṣe alaye wipe awọn yio gba awọn dokita jaburata ti yio ma wo awọn alaisan tọsan toru bẹna si ni awọn nọsi, dẹrẹba mọto ati awọn oṣiṣẹ orişirişi. Nwọn tun fi ye wa iru anfani nlanla ti o mbẹ fun awọn iyawo wa ati awọn ọmọ wa.

## Lofe Ni

Ju gbogbo rẹ lọ nwọn ni awọn yio fi eto ilera yi tọ awọn ara Eko lẹnu wo ni ọfẹ fun ọdun mẹta gbako lai gba epinni lọwọ awọn ara ilu rara.

Boya ọrọ kan ti nwọn gbẹnu kan wipe ninu eto yi ko ni aye fun awọn dokita ti o nşişẹ labẹ Ijọba mọ lati ma ṣe işẹ ẹhin fun ara wọn mọ ni o jẹki gbogbo awọn dokita na faake kọri wipe ati ori ati ọrun awọn ko fẹ ki nwọn gbe eto ilera na jade rara. Ẹnyin ara wa, ẹ ma ka iyoku alaye ijọba nişo on niyi:

KI YIO SI AYE FUN IŞẸ ẸHIN FUN AWỌN 'DOKITA' IJỌBA MỌ

Ni abẹ eto ilera titun fun itọju awọn alaisan ti Ijọba Apapọ ngbero lati gbe kal fun ilo yi, a ko ni gba awọn dokita Ijọba ati awọn oşişẹ miran ti nwọn ba nşişẹ fun eto na ni aye lati tun ma şe işẹ ẹhin, lati ba le ko owo jọ si apo ara wọn mọ. Irin awọn enia ilu Eko nipa iru işẹ ẹhin bayi ti awọn dokita Ijọba ma nşe jẹ eyi ti ko le fun wọn ni igbẹkẹle pe nwọn nri itọju ododo gba, afi bi nwọn tun san owo dokita lọtọ.

Ni abẹ eto titun yi, ẹnikẹni ti o ba nşişẹ fun eto na, ti o ba si tun nşe işẹ ẹhin lati ba le tun ko owo jọ si apo ara rẹ, yio jẹbi ẹşẹ nla, ti o si le jiya dada nitori ẹşẹ yi:

Ireti wa ni pe nigbati olukuluku ba ti mọ wipe ọfẹ ni on le gba itọju fun gbogbo awọn aisan ti o mba on ja, a o ti hu gbongbo idibajẹ nipa gbigba owo abẹtẹlẹ patapata; eyi yio si mu ki awọn enia tun ma ni igbẹkẹle ati ifọkantẹ fun işẹ awọn dokita ati awọn olutọju alaisan.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)


**BE TALLER**

Increase your Height. Details free. Add:— C.T. Hospital, Azad Market,

Delhi 6, India.


# Dokita Kan Nwa Oju Oku Fun Alaiye

PORT—HARCOURT— Dokita onisegun kan ti oruko rẹ njẹ M. C. Peterside ti o mọ arun oju wo mbẹbẹ lọwọ awọn ara ilu Ibo ni ipinlẹ ila orun wipe ki nwọn jọwọ, ki nwọn fun on ni oju oku ẹbi wọn ti ba n ku ki on ri nkan lo fun işẹ woju woju ti on ti kọ.

Dokita Peterside ni on le foju oku si oju afoju alaiye ki o tun ma riran sugbọn oju oku na ni lati jẹ ẹniti o şẹşẹ ku, ti oku rẹ ko ti run rara.

Dokita na ni awọn şe akiyesi iwa kan larin awọn enia ipinlẹ yi ki tete gbe oku wọn wa si ile awọn lakulaku ni gbara ti oku na ba ti ku afi ti o ba ti di nkan ti o nrun ku u.

O ni a jẹ nkan anfani pupọ fun awọn afọju ilu yi ti awọn ẹbi ti oku wọn ba ti ku ba nfun awọn laşẹ lati ma yọ oju wọn fun lilo fun awọn afọju alaiye.

# Iya Kan Pa Oko Re On Na Pokunso

ABAKALIKI— Laipẹ yi ni obinrin kan ti o njẹ Lezi Eze, ẹni ogoji ọdun lọ sodọ awọn ọlọpa ni teşan wọn, o ni on wa jẹwọ nipa ọkọ on ti on ti pa: awọn ọlọpa ilu Abakaleke ni ki o duro ki o sọ ọrọ na fun awọn daradara nitoripe ọrọ na ko ye awọn.

Obinrin ọdaran na tun sọrọ bakanna fun ọga awọn ọlọpa na ni aşalẹ ọjọ na, o ni nitoto ni on pa ọkọ on ti awọn ọ ngbe, awọn ọlọpa si kọ ọrọ rẹ sile, lẹhinti nwọn ti ka a si i leti tan nwọn wa fi ọwọ rẹ bọ'wẹ. Nwọn wa sọ fun un wipe o kẹran elegungun.

Nwọn ni gẹgẹbi ofin obinrin na di apania nitorina o ni lati lọ sọ tẹnu rẹ niwaju adajọ. Ejọ na ni nwọn mu lọ siwaju adajọ Kotu awọn ọlọpa ni ọsẹ ti o lọ'a,

Nigbati o de ibẹ nwọn ka ẹsun rẹ fun un wipe o pa ọkọ rẹ Ododo Ọnake, şugbọn nwọn sun ọjọ igbẹjọ rẹ siwaju. Nigbati awọn ọlọpa mu u pada si ibiti nwọn ti mọle si o ni ki nwọn jọwọ ki nwọn jẹki on lọ sile itọ lati tọ ibẹ ni obinrin na gbe ti mu aşọ ti o ro ti o fi pokunso si.

Nigbati awọn ọlọpa reti rẹ titi, ti nwọn ko ri ni nwọn ba fọ ilẹkun ile itọ, oku rẹ ni nwọn ba nibẹ.

# ELETI–OFE

(A NJU WỌN KOSE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV.NO 883 SATURDAY AUG 24 – AUGUST 30 1963


# Ayiluka Ni: Awon Yoruba Parapo

Bi oju ẹni ba pẹ laiye orişirişi nkan ni a ma nri inu emi Ayiluka si dun lati tun gbọ wipe awọn enia kan ni Ibadan fẹ da ẹgbẹ kan silẹ ti nwọn a ma pe orukọ rẹ ni YORUBA PARAPỌ. Nitotọ o yẹ ki awa, YORUBA PARAPỌ gẹgẹbi awọn orilẹ miran ti parapọ, sugbọn ọrọ na ko nşe ọjọ oni ni o yẹ ki awọn Yoruba Parapọ. Mo mọ nkankan daju, iyẹn ni wipe bi baba nla iya ko ba jẹ awọn ọmọ Yoruba nwọn ki pe nwọn pẹ. Mo niran igbati a da ẸGBẸ ỌMỌ ODUDUWA silẹ nilẹ yi awọn kan bẹrẹsi fi ẹnu ẹtẹ kan an.

Emi Ayiluka mọ wipe eleyi na ko nşe wipe nwọn fẹ da ẹgbẹ Yoruba Parapo silẹ, ere ln nwọn fi nse-AWADA ni gbogbo rẹ. Şe ẹnyin na ti gbọ ti awọn kan ti tẹ alaye iwe jade wipe awọn ko ni ọwọ ninu ọ.ọ Parapọ na? Yoruba ko ti parapọ rara, iọ ni a npa.

## Awon Omo Owa

Mo fẹ ki ẹnyin ọkawe mi, paapa ẹnyin ọmọ Ijẹsha ba mi fi oju agba wo iwe kan ti mo ri gba lọdọ ẹni kan ninu awọn ọkawe mi ti o pe ara rẹ ni Adeyemi ọmọ Ibokun. Ọgbẹni Adeyẹmi na ni ọrọ Ọba Ọwa Ilesha ni o ndun on lọkan pupọ ti on fi kọ iwe na si mi. Oya:

"Lati ọjọ ti Ọba wa Biladu Keji ti waja ni ẹ yin akọwe iwe irohin gbogbo ilẹ Nigeria ti mbere wipe tani yio gun ori oye Ọba Ọwa na." Eleyi kişe nkan ti o le lọdọ awa Ijẹsha şugbọn nkankan ni o fẹ ki ẹniyin ara wa mọ daju, awe, nkan na ni wipe oye Ọba Ọwa kişe oye awọn ara Ilesha ni kan.

'Boya Ọba Ọwa ti jẹ baba fun awọn Ijẹsha ti o wa nile ni o tun jẹ fun awọn Ọmọ mbẹ loko Ijẹsha oke ati awọn Ijẹsha isalẹ ọmọ iya ni gbogbo wa jẹ. Awe, ko yẹ ki a foju pa ara wa rẹ rara nipa ijoko awọn agba ti nwọn fẹ jiroro lori ọrọ Ọba Ọwa tuntun ti nwọn ba fẹ yan ni Ilesha.

'O yẹ ki awọn agba ologboni ilu Ijẹbu, Ijẹsha ati awọn ologboni ilu Ibokun wa, bẹna si ni awọn agba Ijẹsha ti o wa kakiri igberiko.

# Iwe Si Olotu

## Isemo Ko Dara Nitoto

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati kan saara si ọrọ Baba Salẹ ti o sọ laipe yi lori ofin isemọle ti nwọn sọ wipe awọn Ijọba Apapọ wa fẹ fọwọ si lati ma fi de awọn ti nwọn ko ba şe ti nwọn mọlẹ.

Ni ilu gbogbo agbaiye ti nwọn nda iru ofin buruku bayi si ẹ wahala ati darudapọ ni o ma nda silẹ, ko nsi alafia nilu na, aya awọn alamojuto ilu ki balẹ.

Gbogbo awa ilu Nigeria fẹran faaji pupọ, a ko fẹ wahala fun ara wa rara. Nitotọ nigbati a wa labẹ Ijọba Gẹsi nwọn ko fun ni ofin buruku bayi, Kinni o wa mba awọn Minisita alamojuto ilu wa lẹru ti nwọn fi nfẹ şe iru ofin bayi ?

O dabi ẹnpe awa paapa gbagbe orişirişi abuku ti a ti fi kan Ijọba Ghana ati Iselẹ Ilu Afrika lori iru ofin bayi.

O di ọwọ yin, ẹnyin oşelu wa, ofin isemọ ko dara.

Emi ni  
Agege D. Bankọle

## Awon "Oniwayo' Onipulu Tun D !

Olotu, ẹ jọwọ ẹ ba wa sọ fun awọn baba onipulu (football pools) ti o nşe wayo fun wa lọsọsẹ lara owo ti a ba da fun wọn wipe awa na nsọ wọn daradara nisisiyi.

A fẹ ki nwọn mọ wipe ton kọ jọ tana ni ọrọ idije ere pulu (pools) ti ọdun ni. Gbogbo awọn baba oniwayo na ni a o sọrọ aşiri işe wọn fun awọn ọ'ọpa rilo ni nwọn ti nri ida merinlelogun (24 points) ti nwọn nri ni ọsọsẹ.

Gbogbo ara ilu ti mọ wipe orukọ olorukọ ni nwọn fi npurọ wipe nwọn şe orire.

Ninu asiko ọdun ti a sẹsẹ bọ si yi ọpọlọpọ ninu wọn ni yio tun lọ sọgba ẹwọn ti a ba ti yẹdi wọn wo.

Olotu, mo dupẹ lọwọ yin,

Emi ni,  
Isalẹ-Eko Ade Akanbi

## Baba Agbalagba Odaran

Olotu, a ri iwe iwosika kan ti ẹ kọ laipẹ yi nipa ọkan ninu awọn baba agbalagba ọdaran kan ti o fi gbogbo ẹnu sọrọ nipa ofin ihamọle kan ti nwọn fẹ gbe jade.

Mo ti ma ngbọ ti awọn agbalagba Onilakaye ilẹ Yoruba ma nsọ wipe irugbọn ko kọ ogbọn, emi şẹşẹ mọ itumọ ọrọ na ni aipẹ yi ni

Ẹniti o sọ wipe itumọle mduro-rojọ ni o dara fun wa nilẹ ni ko ni lakaye to, nitoripe ti o ba ni lakaye to ni, a nọ wipe awọn Oyinbo ti o jẹ oşelu pataki ko fọmọ wọn soko ẹru ati pe nigbati a wa labẹ wọn nwọn ko fun wa ni ofin ẹru iru eleyi.

Baba ọdaran, aiye dọwọ yin, şugbọn ẹniti o ni oni kọ ni o ni ọjọ ọla.

Emi ni,  
Iludun Paul Adeyẹmi,  
Iẹba Ilọrin

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

'Emi ri wipe ko yẹ ki a foju pa awọn agba Ijẹsha nwọnyi rẹ ti a ba nfẹ ki nkan ma lọ dede. Ọba Ọwa kiṣe Ọba Ilesha nikan, Ọba gbogbo awa Ijẹsha ni i. Emi ni ti nyin nitotọ, Adeyẹmi ọmọ Ibokun"

Adeyẹmi ọmọ Ibokun emi Ayiluka gbọ oro rẹ. Em na ti oro ọrọ Oye Ọwa Ilesha ti igbati Fimajoye Ọba Biladu ti waja wipe iṣẹ pọ pupọ ti awọn ologboni alobaje Ijẹsha ni lati ṣe lori oro na. Jọwọ Ave, tani e fẹ ti ọba Ijẹsha? wọn ẹbi Ajimọtokan ni tabi awọn Ta yero, Orisha Ilesha yio gbe mi.

Eleti - Ofe
D'ARABA


# Jẹki owo rẹ ma dagba si larin ikore kan si ekeji ninu ile Ipamọ Owo ti Barclays

Nigbati o ba ta eso oko rẹ fi owo ti o pa si Ile Ipamọ owo. Fi sabẹ abo nitori igbati o ba nfẹ owo lati fi ra ohun ti iwọ o gbin sinu oko, ogùn ilẹdu tabi irinṣẹ. Nigbati owo rẹ ba si wà ninu ile ipamọ owo ere a ma ti inu rẹ jade ni igba de' gbà.



'Ẹ FI OWO YIN PAMỌ SIBẸ'

Barclays Bank ti ṣe ọpọlọpọ awọran oni sinima ti a ti mọ daṣa to si nderin pani, boya ẹ ti si wọn tẹlẹ. Eyi jẹmọ itan nipa awọn agbẹ mẹta ti wọn ko eso oko wọn lọsi ọja. Ẹnikọkan wọn pa owo pupọ.



Ọkan ninu agbẹ nwọnyi si nkọrin lọ sile to nk'igbe ki gbogbo enia le mọ wipe o ti di olowo. Awọn ọrẹ rẹ si nyá owo lọwọ rẹ, iyawo rẹ ko ri ohunkohun gbà rara. Agbẹ keji fi owo tirẹ pamọ si abẹ ibusùn, sugbọn ole kan ji diẹ lọ ninu rẹ ni alẹ, kòkoro tun jẹ iyiokù.
Agbẹ kẹta logbọn ju wọn lọ.
Gbogbo owo rẹ lo ko lọ tàrata sile Ipamọ Owo rẹ Barclays, ki o ba le ra ohun toba fẹ lati gbin sinu oko ni akoko ati irinṣẹ pẹlu.

Ranti wipe, owo rẹ wà labẹ abo ninu Barclays Bank.

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile iṣẹ won mbẹ hakiri ni orile ede yi.*

# Baba Onisegun Gbowo Lowo Awon Olosa Ki Nwon Le D'ana

JOS — Baba onișẹgun kan ni jẹjẹ on ni on joko sile ti awọn ọlọṣa danadana kan wa gbeșẹ fun on.

Baba onișegun na John Chukwu jẹwọ fun adajọ kotu awọn ọlọpa Ọgbẹni Eman Adewuyi ni ijẹta wipe pọnun mẹtalelogojọ (£163) pere ni owo ti awọn ọlọṣa na wa ko fun on wipe ki on fi șe ogun fun awon ki ọwọ awọn ọlọpa ma le tẹ awọn.

Orukọ awọn ọdaran mẹta ti awọn ọlọpa mba șe ẹjọ wipe nwọn dana nwọn si gba owo lọwọ ẹni ẹlẹni ni Sunday Omega, Odigbo Okadigbo ati Nwafor Okonkwo.

Baba Onișegun na ni awọn bẹ on wipe ki on sin wọn lọ si ibiti nwọn gbe ti nlọ dana na. Onișegun yi ni ẹmeji ti on ba awọn ọdaran na lọ dana, awọn ri nkan șe daraddra.

Baba onișegun yi ni alẹ ọjọ kan pọnun mẹdọgbọn ni nwọn ha on, șugbọn lọjọ ti awọn ri ọgọrun o din legbeje pọnun (£1,313) gbe lọwọ awọn ti awọn lọnapọnun mọkanleladọfa (£111) ni nwọn pin fun ninu owo na.

Ẹlẹri yi ni mọto ni awọn awọn ngbe lọ fi dubu ọna fun awọn ero lọna ti nwọn npe ni Akwanga. O ni lalẹ ọjọ kan awọn ọlọpa fẹrẹ mu awọn, nșe ni awọn sa sinu igbo nigbati awọn ri mọto awọn ọlọpa ti mbọ nibiti awọn gbe fẹ dana.

Baba onișegun na ni tibọntibọn ni awọn nlọ dana na, awọn a si sọ fun awọn ero ti awọn ba ri wipe ki nwọn bọ silẹ ninu mọto, awọn a si gba gbogbo owo ọwọ wọn yatapata.

Nwọn ko ti pari ẹjọ wọn na.

---

# Nwon Fe Pa Eko Ofe Re Ni Ipinle Tuntun

BENIN CITY — Olotu Ijọba Ipinlẹ agbedemeji Iwọ Orun ti nwọn șẹșẹ da silẹ, Oloye Dennis Osadebay pẹlu awọn ajẹlẹ ti nșe isangbe rẹ ti gunlẹ si ilu Benin ti nwọn fi șe olu ilu ipinlẹ na, ni ọsẹ ti o kọja. Ni ijarun ọjọ Aje ni a gbọ wipe gbogbo awọn ajẹlẹ ti a wa labẹ rẹ șe ibura, gbogbo wọn si ti bẹrẹsi șe eto ișẹ ti nwọn yan wọn si.

Irohin kan pataki kan ti a gbọ nipa eto ijọba ipinlẹ tuntun na ni wipe nwọn fẹ pa eto ẹkọ-ọfẹ rẹ patapata kakiri gbogbo ipinlẹ tuntun na nitoripe owo eto ẹkọ-ọfẹ kișe owo kekere rara: Ijọba ti o ba fẹ fun awọn aro ilu ni ẹkọ-ọfẹ ni lati bọ șokko girigiri.

O di ọdun kẹjọ gbako nisisiyi ti awọn alamojuto Ijọba ipinlẹ IwọOrun ti da ẹkọ yi silẹ fun anfani awọn ọmọ awọn ti o wa labẹ, ninu wọn si ni awọn ara ipinlẹ agbedemeji ti nwọn ya lọ si wa nigbana.

Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun ni ijọba kinni ni ilẹ Nigeria ti o kọkọ da ẹkọ ọfẹ. Ijọba Ipinlẹ Ila Orun to gbidanwo wipe ki awọn na ja ruburuba lori eto ilewe ọfẹ jabọ. Omi ni o pọ lẹhin ẹja ni ti awọn alamojuto Ijọba Apapọșe Eko lori eto ilewe ọfẹ ti wọn na.

Ọgbẹni James Otobo tișe ajẹlẹ inawo fun ipinlẹ tun tun nașe alaye wipe nkan ti awọn fẹ nawo le lori ni sisiyi ni rọba ti awọn ngbin nitoripe igi koko (cocoa) awọn niyẹn. Ko si ọna ti owo le wọle gba fun awọn ju yi lọ.

---


A Nfe Asoju Fun Iwe Irohin Eleti-Ofe

LATI AWON ILU OKERE



SELF ASSURED

OR

LIFE ASSURED

The modern man and woman will feel more self assured when life assured with the:-

GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,

(INCORPORATED IN NIGERIA)

Enquire now for full details of our low cost endowment policy.

HEAD OFFICE:

39-41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 25251.

BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

# Warm Welcome For Nigerian Pastor In Britain

LONDON – A warm welcome and a real community of interest awaits a Nigerian church minister who is to work in a British parish for a year.

For Mr. J. Adebayo of Ibadan who next month joins one of the largest parishes in Birmingham as a curate will find there a vicar with a family tradition of service in Nigeria.

He will be joining the Rev. John Wilson, of St. John's Sparkhill. Mr. Jackson's father, the Rev Joseph Wilson Jackson, now retired and living in Surrey spent many years in Nigeria up to 1924 with the Church Missionary Society.

"It will be a great pleasure to welcome Mr Adebayo," Mr Jackson told our correspondent recently. My father served in many parts of Nigeria and has talked much about life there."

'Mr Adebayo will find we have a very busy time in a parish such as St. John's," explained Mr. Jackson. 'We serve 20,000 people and have a day school attached to the Church. In the parish there is also a hospital where we visit patients regularly and many industrial concerns we call on. Our curates also do a considerable amount of youth work."

Mr Adebayo will be taking parts in all the aspects of parochial work in this large evengelical parish.

# New Cocoa Crops For World Market

LONDON – The next milestone in the cocoa year will be the start of the marketing of the new West African crops which is expected within the next few weeks, say the London cocoa dealers, Gill and Duffus, in their monthly report just published.

"Supply prospect from West Africa have continued to improve during the past month. The intermediate crops in that part of the cocoa world, especially in Ghana, the main area have out-turned at record levels and prospects are still bright for the developing main crops in West Africa to be harvested in the autum,' they report.

The present forcast of world grinding for the calendar year 1963 is 1,162,000 tons; this is a 6 per cent increase on 1962 which was itself 6 1/2 per cent rise on 1961.

Cocoa grindings for Britain, America, Holland and France-four of the five main consuming countries-show an increase of 41/2 percent in the first half of this year compared with same period last year.

In Britain cocoa, bean grindings in the second quarter of this year totalled 25,400 tons-a rise of 5 per cent on the same period last year. And the first six months' total of 51,000 tons is the best since the first half of 1963, the dealers state, and 3 per cent up on the same period last year.

# 'Family Group' Nursery Schools Inspected In London

LONDON – Nursery schools run on the 'family group' system have particularly interested Mrs Okpara and Mrs Mokelu, who ended a week's visit to Britain yesterday

The eminent Nigerian ladies, who have been guests of the British Government, had been visiting the Mary Hughes Day Nursery, run by the London County Council, where they were shown round by the Matron, Miss M. Olive, Both expressed considerable interest in the way the children are handled in small family type groups rather than by age.

"Except for infants, we group the children in family groups in which a number of children of different ages share their own room in the nursery. We feel that this system is more like a home and much more natural, " Miss Olive explained

The nursery has sixty children up to the age of five and there is a staff member for every for children. The nursery olso runs two year courses for training girls to take the national Nursery Examination Board examinations.

## Biggest Oil Tanker Launched

BELFAST – The biggest tanker launched in Britain the 85,500 tons deadweight RIMFONN glided from Slipway 14 at the Belfast (Northern Ireland) shipyards of Harland and Wolff Limited, recently.

Eight hundred and Seventy feet long, the RIMFORNN is the longest vessel ever built in Belfast. It is 20 feet longer than the liners TITANIC, OLYMPIC and BRITTANIC and 50 feet longer than the CANBERRA, also built on Slipway 14 of the Harland and Wolff yard.

The RIMFONN, built for the Bergesen, Group Stavanger, Norway, and launched by Mrs. Ragny Bergesen, wife of the senior director of the Group is the first vessel to come from the modernised slipways planned for super tankers of up to 1[illegible]0 tons deadweight

Shortly the keel of [illegible] bigger tanker [illegible] is to [illegible] the same [illegible] has been [illegible] by the [illegible] Oil Company.

# Alaye Eto Ilera

(O bere loju ewe keta)

ILERA LORO: ETO ILERA TI O SE NFANI FUN AWON OSISE JULO NI YI

Gbogbo anfani ti o wa ninu eto titun fun ilera ati itoju awon alaisan yi ni awon omoran ise ilera kakiri agbaiye ti kan sara si pe nwon je okan ninu awon ti o gboro julo ni ori ile aiye. Loto se, nwon ti kan sara si eto na gegebi eleyi ti o se awon osise ni anfani julo nipa oro ilera.

Titi de ibi ti a ba de yi, ori iwe nikan ni eto na ti han; bi ala ni o si ti nri fun opolopo enia.

Ona kansoso ti a fi le mu ala yi se ni pe ki gbogbo enia ti eto na yio ba se ni anfani fowosowopo ni otito ati ni ododo. Nitoto, Ijoba Apapo ni yio na eyi ti o ju ninu owo tabua ti ao fun lori eto na, sugbon owo awon enia ilu Eko fun ara won ni akoso ati abojuto gbogbo ise na wa.

Beni, ki i se ero Ijoba Apapo ni lati se eto dada bayi fun Eko nikan, sugbon nitoripe Eko je ilu ti oniruru enia fi se ibugbe won, ti o si je olu-ilu nibiti gbogbo awon enia orile-ede yi ti ma npade, ohun ti o to, ti o si ye ni pe ki a bere eto na ni Eko.

Iriri ti a ba ni nipa bi eto na ba ti sise ti si ni Eko ni a o wa mu lo, ni ona ti yio tun dara si fun awon ilu nlanla miran ni rile-ede Naijiria, gegebi Kano, Port Harcourt, Ibadan, Enugu ati Kaduna

(O Pari)

# Oloye Ashogbon Jalaisi

EKO— Anu se ni lati gbo iku Sulu, Oloye Ashogbon ti o jalaisi ni oru ana ninu Afin Ashogbon ni Isale Eko, eni odun metadinlogota ni Oloye na. A ko ti mo ojo ti nwon yio sinku re boya ni ola lojo Sunday ni.


*AFRICAN SPECIAL*

- ★ Full tropicalisation and underbody protection plates.
- ★ Strong and comfortable suspension.
- ★ Outstanding road holding.
- ★ Modern workshops and spare parts stores manned by Factory Trained Staff.
- ★ HIGH RESALE VALUE.

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, (E.B.) IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

— Sub-Distributors: —

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.


# Gbanjo! Okunrin Kan Lu Gbajo Ara Re

(o bere loju ewe kinni)

Ogbeni na ni ponun merindilogun (£16) ni on ngpa lososе nibiti on nsise sugbon awo na ko ka oju ilu rara, o ni gbese kan ti on je ngbati iyawo on jalaisi ninu iwon nkan bi osu marun sehin mba on lokan je pupo. O ni on ni on ra ile ti nwon sinku na si ati owo dokita ti o wo obinrin na.

O ni obinrin ti o ba ra on na ni yio ni awon omo on mererin on a si ma se oko re. Ogbeni yi ni ko si iberu nibe nitoripe moto ayekele wa ti awon yio ma fi se igbadun pelu iyawo tuntun yi. Ki obinrin na ki o sa ti ba on san ojidinlegberun ponun ti on je ni gbese yi.

Baba ti o fe ta ara re fobinrin yi ni on ko fe arugbo. obinrin ti ojo ori ko ba ju eni odun mejidinlogbon tabi merindilogoji lo ni on nfe.

KILOSE TI AWON SOJA WA KO LE KO AFARA?

# Dokita Obinrin Kan Ni On Fe Mo Idi Eyi

( O bere loju ewe kinni )

O ni ikun omi yi nkan kekere loje loju awon soja jagunjagun ilu miran, ko si to nkan ti o le se won lona rara bi ko ba je awon soja ilu ti wa yole ni o ye ki awon ko afara (bridge) pajawiri si oju ona larin ojo meta,

Dokita obinrin na ni ko da on loju wipe awon soja wa na mo ise ti a gba won fun. O ni ise won kise ki a ma yan niwaju awon alejo oselu tabi ki a ma wa awon ti o fe dite si Ijoba kakiri, O ni awon soja yi wa fun iranlowo awon ara ilu lati ma da abo bo won larin ilu, loko lodo ninu oja ati nibikibi,

O ni ti awon soja na ba se eyi ni awon to mu owo wa funa, Enyin oga soja, oro niyi o!

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos
Phone 23370; Editor: (Olotu) Ola. Onatade, 15.Kos... Street, Lagos, Box 457